ONDO JOURNAL OF ARTS, 2 (1), 2026
Journal homepage: https://ojaafued.com/index.php/ojall
Recieved 20.11.2025, Revised 02.01.2026, Accepted 10.03.2026,
Published 30.04.2026
ISSN:1597-104X

# ÀGBÉYẸ̀WÒ ÌṢỌWỌ́LÒ-ÈDÈ INÚ ORIN ÀJÀGBÓ NÍ Ọ̀GBÀGÌ-ÀKÓKÓ

Ayọ̀bámi Mistura TÁBÍ-ÀGÒRÒ, Ph.D.
&
Wahab Táíwò BÁKÀRÈ

**_Àṣamọ̀_**
*Orin nínú ọdún ìbílẹ̀ jẹ́ ọ̀kan lára àwọn adùn tó ń mú kí ọdún ìbílẹ̀ ṣe é wò. Ọ̀pọ̀ ọdún bí ọdún Egúngún, Imọlẹ̀, Ògún, Ọjà-Olorì àti Àjàgbo ni wọ́n wà ní ìlú Ọ̀gbàgì-Àkókó, tí ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn sì ní orin nínú. Iṣẹ́ yìí fẹ́ wo àwọn orin inú ọdún Àjàgbó ní ìlú Ọ̀gbàgì-Àkókó, nítorí pé ó jẹ́ ọ̀kan lára àwọn orin ọdún ìbílẹ̀ tó ṣe pàtàkì jù láàrin àwọn orin ọdún ìbílẹ̀ ní Ọ̀gbàgì-Àkókó, ìdí nìyí tí a fi yan orin ọdún náà fún iṣẹ́ ìwádìí yìí. Bákan náà, ọ̀pọ̀ àwọn onímọ̀ ìṣáájú ni wọ́n ti ṣe onírúurú iṣẹ́ lórí iṣọwọlò-èdè láti wo bí àwọn ọ̀kọrin tàbí olùṣẹ̀dá iṣẹ́-ọnà aláwòmọ́ lítíréṣọ̀ kan ṣe ṣọwọ́ lo èdè nínú àwọn iṣẹ́-ọnà aláwòmọ́ lítíréṣọ̀ tí wọ́n gbé kalẹ̀, ṣùgbọ́n iṣẹ́ kò tíì rinlẹ̀ tó lorí wíwo ìṣọwọ́lò-èdè nínú àwọn orin inú ọdún Àjàgbó ní ìlú Ọ̀gbàgì-Àkókó, àlàfo tí ó ṣí sílẹ̀ yìí ni iṣẹ́ yìí fẹ́ dí. Iṣẹ́ yìí wo àwítúnwí odidi gbólóhùn, àwítúnwí àkùdé gbólóhùn, ìbéèrè-pèsíjẹ, àfiwé tààrà, àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́, àkànlò-èdè àti àyálò-èdè inú àwọn orin ọdún Àjàgbó. Àbájáde ìwádìí yìí ṣe àfihàn àwọn kókó pàtàkì tí wọ́n wà nínú àwọn orin inú ọdún Àjàgbó tí a yàn láàyò, ó sì tún sọ nípa akitiyan àwọn akópa inú ọdún náà lórí ìlò-èdè wọn. Abala ọ̀nà ìṣàwòjíji nínú tíọ̀rì ìfojú-ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbépọ̀-wo-lítíréṣọ̀ tí ó rí lítíréṣọ gẹ́gẹ́ bí àwòjíji àwùjọ ni tíọ̀rì tí yàn fún iṣẹ́ yìí.*
**_Kókó-Ọ̀rọ̀_**: *Ìṣọwọ́lò-èdè, Ọdún ìbílẹ̀, Orin Àjàgbó, Ọ̀gbàgì-Àkókó, Tíọ̀rì ìfojú-ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbépọ̀-wo lítíréṣọ̀.*

**_Abstract_**
*Song in traditional festivals is one of those aesthetic features that makes a festival suitable for viewing. There are many*





*festivals in Ọ̀gbàgì-Àkókó, which include Egúngún, Imọlẹ̀, Ògún, Ọjà-Olorì, and Àjàgbo festivals, in which they each have songs as a major feature. This work is focused on Àjàgbó's songs in Ọ̀gbàgì-Àkókó, because it is one of the most important festival songs amongst traditional festival songs in Ọ̀gbàgì-Àkókó, which is why the festival songs are purposively selected for this research work. Several early literary critics have carried out several stylistic analyses in order to examine how singers and literary artists have successfully used stylistic features in their literary creations, but stylistic features in Àjàgbó festival songs in Ọ̀gbàgì-Àkókó has not attracted much attention; this is the gap this research work tends to bridge. This study examined total repetition, partial repetition, rhetorical question, simile, metaphor, idioms, and loan words in Àjàgbó festival songs. The result of this research establishes the importance messages embedded in the selected Àjàgbó's festival songs and also portrays how performers of the festival are skilled in their use of language. The mirror image approach of the sociology of literature, which sees literature as the direct reflection of society, is the suitable theory for this work.*
**_Keywords_**: *Stylistics, Traditional festivals, Àjàgbó's songs, Ọ̀gbàgì-Àkókó, Sociology of literature.*

## Ìfáárà

Ọdún Àjàgbó bẹ̀rẹ̀ ní ìlú Ọ̀gbàgì-Àkókó ní ọ̀rúndúnkejìdínlógún (18th century) sẹ́yìn. Tọmọdé tàgbà, ọkùnrin àti obìnrin ni wọ́n máa ń kópa nínú ọdún náà ṣùgbọ́n láyé òde-òní, ìwọ̀nba nínú àwọn àgbàlagbà ló kù tí wọ́n ń kópa nínú ọdún yìí. Bí ọdún Àjàgbó ṣe ń tú àṣírí ìwà ìbàjẹ́ bí àgbèrè, ṣíṣe, pánṣágà ṣíṣe, ìwà olè, ìjínigbé; bẹ́ẹ̀ náà ló tún máa ń fààyè sílẹ̀ fún ìrẹ́pọ̀ láàrin àwọn ènìyan ìlú Ogbàgì-Àkókó.

Orin ò kàn déédé máa ń wáyé nínú ọdún Ajàgbó láìní ìdí. Orin ọdún Àjàgbó gan-an ló ṣe pàtàkì jù tí àwọn òǹwòran ọdún Àjàgbó níláti máa fọkàn sí, nítorí pé ibẹ̀ ni wọn yóò ti rí ẹ̀kọ́ tó sodo sínú ọdún náà kọ́. Lẹ́yìn pé ìmúra àti ìmọ̀sílára àwọn akópa a tún máa mú ìtùlára bá ènìyàn, èyí tó kù nínú eré Àjàgbó, eré lásán ni. Inú orin Àjàgbó ni àṣírí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ láabi tí ó ti wáyé láti ọwọ́ àwọn

aráàlú sẹyìn ti máa ń tú, tí ohun tí ọ̀pọ̀ ti hù níwà láìdára yóò ti hànde. Àwọn tó jẹ́ ọ̀kọrin Àjàgbó yìí ló màa ń fimú fínlẹ̀ bí ajá ọba, láti máa wádìí nípa àwọn ìwà ìbàjẹ́ tí aráàlú ti hù séyìn. Orin yìí ni wọn yóò máa fi gbé àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ wọ̀nyí síta séti ìgbọ́ àwọn tí ìṣẹ̀lẹ̀ náà bá ṣókùnkùn sí. Ìdí nìyí tí orin yìí fi ṣe pàtàkì nínú ọdún Àjàgbó. Orin Àjàgbó jẹ́ orin ìfẹ̀hónúhàn, ó sì tún kún fún ẹ̀fẹ̀. Orin tó ń pa ẹni tí wọ́n ń kọrin bu lẹ́kún, ẹ̀rín ni àwọn olórin Àjàgbó fi ń ṣe. Èyí jọ ẹ̀fẹ̀ àti ìwèrénde inú orin ìjálá tí wọ́n jẹ́ gbòógì nínú lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá. Ohun kan tí ó kàn yà wọ́n sọ́tọ̀ ni ti ìwúlò àti àsìkò tí à ń lò wọ́n láwùjọ. Ẹ̀wẹ̀, ìṣọwọ́lo-èdè inú àwọn orin Àjàgbó tí a gbàjọ ní ìlú Ọ̀gbàgì-Àkókó ni a fẹ yẹ̀ wò nínú iṣẹ́ yìí.

## Ohun tí àwọn Onínọ̀ sọ nípa Orin

Orin jẹ́ ọ̀nà kan pàtàkì tí à ń gbà fi èrò ọkàn wa hàn yálà nígbà adùn tàbí ìkorò lọ́nà ìgbóhùnsókè ga ju ìpèdè ojoojúmọ́ lọ. Yorùbá a máa kọ orin pẹ̀lú ìlù lílù, ijó jíjó, àtẹ́wọ́ pípa tàbí kí wọ́n dá orin náà kọ láìlo ohun-èlò kankan. Délànọ̀ (1958) ní; "…orin jẹ́ ohùn pẹ̀lú ọ̀rọ̀ tí ó dùn". Bí a bá wo ohun tí onímọ̀ yìí sọ dáadáa, a óò rí i pé ìtumọ̀ tí ó fún orin kò jinlẹ̀ tó láti fún wa ní ìrísí àti àbùdá ohun tí a lè pè ní orin láwùjọ Yorùbá. Gbogbo ewì alohùn Yorùbá ni wọ́n ń lo ohùn pẹ̀lú ọ̀rọ̀ dídùn fún, èyí tí ó yàtọ̀ sí ìpedè ojoojúmọ́. Dárámọ́là àti Jéjé (1967) ṣàlàyé pé ìfẹ́ tí àwọn Yorùbá ní sí ìlù, orin àti ijo kò kéré. Wọ́n tẹ̀ síwájú pé ìlú, orin àti ijó ti dí ohun ìrandíran ní ilẹ̀ Yorùbá. Nítorí pé láti ìgbà ayé baba ńlá wa ni nnkan wọ̀nyí ti bẹ̀rẹ̀. Èyí tilẹ̀ máa ń hàn nínú orin àwọn aludùndún pé, 'ìwọ le jó, èmi le lù kòkòrò méjì lo pàdé. Èyí fi yé wa pé orin kíkọ kì í ṣe ohun tí ó ṣẹ̀ṣẹ̀ bẹ̀rẹ̀ ní àwùjọ Yorùbá. A lè fi kún àlàyé Dárámọ́là àti Jéjé (1967) yìí pé kì í ṣe àwùjọ Yorùbá nìkan ni orin ti ṣe pàtàkì, ṣùgbọ́n káàkiri àgbáyé ni ó ti gbayì, tí wọ́n sì ń lò ó ní onírúurú ọ̀nà. Nítorí náà, onímọ̀ yìí fi kún àlàyé wọn pé, ìlù lílù, orin kíkọ àti ijó jíjó ti di àjogúnbá fún gbogbo ọmọ Yorùbá pátá lóde òní.







Ajíbóyè (2003) jẹ́ kí ó di mímọ̀ pé orin jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ewì alohùn Yorùbá. Ó tún fi orin hàn gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ àtínudá tí ó jinlẹ̀ láàrin àwọn ewì alohùn ilẹ̀ Yorùbá yòókù. Bákan náà ni a tún rí fàyọ nínú iṣẹ́ Ajíbóyè yìí pé orin kì í ṣe iṣẹ́-ọnà kan ṣákálá, ohun tí ó mú ìrònú ijinlẹ̀ àti àkíyèsí ọ̀rọ̀ tí ó ń lọ ni àyíká ẹni lọ́wọ́ ni. Awólúsì (2012) ṣàlàyé ohun tí Euba sọ lórí orin pé, ó dà gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà tí a fi ń to ìró pọ̀ láti fi ẹwà kún ohun tí ó jẹ́ èrò ọkàn ẹni. Onímọ̀ yìí gbìyànjú láti wá ìtumọ̀ fún ohun tí a pè ní 'orin', àmọ́, ó gbàgbé láti fi kún àlàyé rẹ̀ pé gbogbo lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá ni ó jẹ mọ́ títo ìró pọ̀ láti fi èrò ọkàn ẹni hàn.

Ilésanmí nínú Ọláwálé (2015:83) sọ nípa orin báyìí pé; "Orin ni ìgbésẹ̀ ṣókíṣókí tí a pín ní dọ́gba-n-dọ́gba tàbí tí ọ̀kan kò ju èkeji lọ, tí ó sì gbọ́dọ̀ bá dídún ohùn ìlù mu." Àwọn onímọ̀ yìí fí ń yé wa pé ohun tí ó lẹ́tọ̀ọ́ gbáà ni pé, kí orin ní ìgbésẹ̀ ìwọ̀ntun-wọ̀nsì nínú, kí ó sì bá dídún ohùn ìlù mu. Àkíyèsí fi hàn pé èrò rẹ̀ yìí fi àjọṣepọ̀ tí ó wà láàrin ijó, ìlù àti orin hàn. Scholes nínú Ọláwálé (2015:81) sọ pé "song is a natural means of self expression". (Orin jẹ́ nǹkan àdámọ́ tí a fi máa ń gbé èrò ọkàn ẹni síta.). Èyí túmọ̀ sí pé, ẹ̀bùn tí Ọlọ́run ti fún ènìyàn láti ọ̀run wá ni ohun tí orin jẹ́. Rájí (2015:23) náà gbìyànjú láti fún orin ni ìtumọ̀. Ó sọ pé:

> Orin ni a lè pé ní ìfohùndárá tó ní ẹwà ìpèdè bí àwìtúnwí, àfiwé àti ìgbésẹ̀ dọ́gbándọ́gba lọ́nà tí a lè wọ́ ohùn nílẹ̀ ní èyí tí yóò fún wa ní bátàni tàbí òté kan tí kò ní jẹ́ kí orin sú ènìyàn gbọ́, tí ó si ní ìtumọ̀, tí ó tún jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà fún àwọn ènìyàn àwùjọ. A lè lu ìlù sí i, a sì lè kọ ọ́ lọ́bọ̀rọ́.

Rájí (2015) ṣàlàyé nípa àwọn àbùdá tí orin gbọ́dọ̀ ní, a lè sọ pé orin ni ohùn ẹnu tàbí èlò tí a fi ń gbé èrò ọkàn ẹni jáde ní ọ̀nà àrà, tí ó ní ẹ̀yà ìpèdè àti ìgbésẹ̀ dọ́gba-n-dọ́gba, tí yóò sì tún ní ìtumọ̀ tí àwùjọ tẹ́wọ́ gbà.

Òjó àti Sa'adu (2018) ṣiṣẹ́ lórí ipa tí èdè Yorùbá máa ń kó nínú orin ìtàpórógan tó máa ń wáyé ní àsìkò ìdìbò àti nínú ètò ìṣèlú

mìíràn tí ó wà ní àwùjọ Yorùbá. Àwọn onímọ̀ yìí jẹ́ kó yé wa pé oríṣìí àyọrísí búburú ni orin ìtàpórógan yìí lè fà láwùjọ. Wọ́n pín àwọn ohun tí ó lè ṣatọ́kùn ìtàpórógan yìí sí ọ̀nà mẹ́ta: ìhùwàsí, ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ tàbí àyíká ẹni, àti bí a ti ṣe le kó ara ẹni ní ìjánu. Bákàrè (2025) ṣiṣẹ́ lórí orin inú ọdún Túnlá tó jẹ́ ọdún èwe tí ó màa ń wáyé ní àdúgbò Eegun ní ìlú Ọ̀gbàgì-Àkókó. Ó ṣàlàyé nípa àwọn ìdí pàtàkì tí orin náà fi ń wáyé láàrin àwọn ọmọdé tí wọ́n jẹ́ obìnrin, ó sì tún ṣe ìpínsísọ̀rí orin náà, láti fi ìwúlò orin Túnlá náà hàn.

**Tíọ́rì Ìṣàmúlò: Tíọ́rì Ìfojú-ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbépọ̀-wo-Lítíréṣọ̀**

Hippolyte Taine (1828-1893), Escarpit (1968 & 1971) àti akẹgbẹ́ wọn yòókù ni wọ́n ṣe agbátẹrù tíọ́rì yìí. Ojú ohun tí ó ń ṣẹlẹ̀ ní àwùjọ ni àwọn agbátẹrù tíọ́rì yìí ń wò nínú afọ̀ lítíréṣọ̀, láti tan ìmọ́lẹ̀ sí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tó ń wáyé ní àwùjọ. Níwọ̀n ìgbà tó jẹ́ pé kò sí ohun tó wà nínú àwùjọ tí kò lè fara hàn nínú lítíréṣọ̀ àwùjọ kọ̀ọ̀kan, ìwúlò lítíréṣọ̀ yóò tayọ ọ̀rọ̀ àwàdà tàbí ẹ̀fẹ̀ lásán. Èyí gan-an ni èrò àwọn agbátẹrù ìfojú-ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbépọ̀-wo-lítíréṣọ̀. Adéyẹmí (2006:31) sọ nípa ìfoju-ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbépọ̀-wo lítíréṣọ̀ pé:

> … Sosíọ́lọ́jì lítíréṣọ̀ ni ẹ̀kọ́ ìmọ̀ nípa ìbáṣepọ̀ tó wà láàrín lítíréṣọ̀ àti àwùjọ. Ohun tí èyí túmọ̀ si ni pé lítíréṣọ̀ kan kò wà lásán, tí a bá sì fẹ̀ ṣe àgbéyẹ̀wò rẹ̀, a níláti fi èyí sọ́kàn, nítorí pé a kó lé ya lítíréṣọ̀ àti àwùjọ tí a ti bí i sọ́tọ̀.

Àkíyèsí tí a ṣe lórí ohun tí Adéyẹmí (2006:31) sọ nípa sosíọ́lọ́jì ni pé, àjọṣepọ̀ wà láàrin lítíréṣọ̀ àti àwùjọ tí wọ́n ti bí i. Fún ìdí èyí, bíi máyàmí ajá ọdẹ ni ọ̀rọ̀ nípa lítíréṣọ̀ àti àwùjọ ṣe rí, a ò lè yà wọ́n kúrò. Ọ̀pẹ́fèyítìmí (2014:121) náà fi hàn nínú iṣẹ́ ìwádìí rẹ̀ pé:

> Sociology of literature is a branch of literary study that examines the relationship between literary works and their social contexts, including… kinds of audience… dramatic presentation, and the social positions of authors and readers.





> Soṣíọ́lọ́jì lítíréṣọ̀ jẹ́ ẹ̀ka ìmọ̀ lítíréṣọ̀ kan tó n ṣàgbèyẹ̀wò àjọṣe láàrin iṣẹ́ lítíréṣọ̀ àti ọgangan-ipò wọn láwùjọ, pẹ̀lú… irúfẹ́ olùgbọ́… ìlànà ìṣèré àti ipò ònkọ̀wé àti ònkàwé.

Ohun tó ṣe pàtàkì nínú àyọlò òkè yìí ni àjọṣepọ̀ tó wa láàrín lítíréṣọ̀ àti àwùjọ tó ni lítíréṣọ̀ náà. Àwùjọ àti lítíréṣọ̀ kò ṣe é yà sọ́tọ̀ síra wọn.

Abala ìṣàwojíji àwùjọ inú tíọ́rì ìfojú-ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbépọ̀-wo-lítíréṣọ̀ ni a lò fún iṣẹ́ yìí. Ó fi lítíréṣọ̀ hàn gẹ́gẹ́ bí irinṣẹ́ àwùjọ tí ó máa ń sọ nípa ẹ̀dá ènìyàn inú àwùjọ àti àṣà wọn. Madame de stale (1766-1817), H. A. Taine (1828-1893) àti Louis de Bonald (1754-1840) tí wọ́n ṣagbátẹrù tíọ́rì yìí ṣàlàyé pé nípa fífi ara balẹ̀ ka èyíkéyìí lítíréṣọ̀ orílẹ̀-èdè kan, a lè sọ púpọ̀ nípa irúfẹ́ orílẹ̀-èdè bẹ́ẹ̀. Èyí túmọ̀ sí pé bí a bá ṣe àwòfín iṣẹ́-ọnà ajẹmọ́-lítíréṣọ̀ agbègbè kan pàápàá jù lọ lítíréṣọ̀ Yorùbá, ìbáṣepọ̀ mọ̀lẹ́bí, àyípadà, àṣà àti ọ̀nà ìgbé-ayé àwọn èniyàn ibẹ̀ ni a ó mọ̀. Ọ̀nà ìṣàwojíji àwùjọ yìí tún ṣàlàyé pé àwọn ayẹyẹ inú iṣẹ́-ọnà kì í ṣe àtinúdá èrò olùṣẹ̀dá iṣẹ́-ọnà lásán, bí kò ṣe pé wọ́n fi wọ́n ṣe àwòjíji àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ kan nínú àwùjọ. Nínú àwọn orin Yorùbá, ìhùwàsí ènìyàn, ìbágbépọ̀ wọn àti bí wọ́n ṣe ń fi èdè bá ara wọn sọ̀rọ̀ àti bí wọ́n ṣe fi ń hùwà láàrin ara wọn ni abala ọ̀nà ìṣàwòjíji yìí ń tẹpẹlẹ mọ́.

Ọ̀pọ̀ ìwà ìbàjẹ́ bí ìwà olè, ojúkòkòrò, ìwà ọ̀lẹ, àgbèrè ṣíṣe, àti àwọn ìwà ìbàjẹ́ mìíràn, bí wọ́n ṣe máa ń fara hàn nínú àwùjọ ni ó kún ọwọ́ ọ̀pọ̀ àwọn olùgbé ìlú Ọ̀gbàgì-Àkókó tí wọ́n ni orin Àjàgbó tí a yẹ̀ wò nínú iṣẹ́ yìí. Irúfẹ́ àwọn kókó-ọ̀rọ̀ yìí ni abala tíọ́rì ìfojú-ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbépọ̀-wo-lítíréṣọ̀ tí a lò yìí ń ṣe àwòjíji wọn nínú àwùjọ. Ẹ̀wẹ̀, àtòpọ̀ àwọn ìró èdè Yorùbá tí a fi ń gbé orin jáde nínú àwùjọ ni ó máa ń wáyé láti ọwọ́ àwọn ènìyàn inú àwùjọ yìí, ọgbọ́n lílò àwọn èdè wọ̀nyí láti ṣàlàyé àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú àwùjọ lọ́nà tó mú ìgbádùn ajẹmẹ́wà lọwọ́ wà lára pàtàkì ohun tí tíọ́rì yìí ń ṣàlàyé.

**Ìṣọwọ́lò-Èdè Inú Orin Àjàgbó ní Ọ̀gbàgì-Àkókó**

Ìmọ̀ isọwọ́lò-èdè dà gẹ́gẹ́ bí ìtẹnumọ́ àti àfikún tí a fi kún èrò tàbí làbárè lásán, tí ó sì hàn nínú ètò èdè tí à ń fọ̀ láìkóbá ìtumọ̀ rẹ̀ (Riffaterre, 1959). Láméètọ́ tó bá gbá iṣẹ́-ọnà aláwòmọ́-lítíréṣọ̀ kan mú gbọdọ̀ lè ṣàwárí ohun tó wà lódò ikùn apohùn tàbí òǹkọ̀wé.

**Àwítúnwí**

Àwítúnwí jẹ́ ọnà-èdè tó wà fún itẹnumọ́ kókó-ọ̀rọ̀ pàtàkì nínú afọ̀, lítíréṣọ̀ alohùn tàbí lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ. Nígbà mìíràn, iṣẹ́ ìsọ̀yè ni àwítúnwí ń ṣe nínú afọ̀. Bí apohùn tàbí òǹkọ̀wé ṣe ń ṣe àtúnwí abala tàbí odidi gbólóhùn inú afọ̀ ni yóò máa ran àwọn olùgbọ́ tàbí òǹwòran lọ́wọ́ láti tètè ní ìrántí ohun tí wọ́n gbọ́ tàbí èyí tí wọ́n kà. Ọ̀kan pàtàkì nínú ọnà-èdè inú lítíréṣọ̀ ni àwítúnwí jẹ́. Àwítúnwí odidi gbólóhùn àti àkùdé gbólóhùń ni iṣẹ́ yìí yóò yẹ̀ wò.

**Àwítúnwí Odidi Gbólóhùn**

Lábẹ́ àwítúnwí yìí ni a ti máa ń ṣe ìtẹnumọ́ ìlà láìmọye ìgbà. Àwítúnwí yìí ni ọnà-èdè tí a máa ń lò láti tọ́ka sí odidi ìhun gbólóhùn tí gbogbo fóníímù, mófíìmù, sílébù, wúnrẹ̀n, àpólà àti gbogbo àmì asòrọ̀pọ̀ pẹ̀lú àwọn ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ inú wọn kò ti gbọ́dọ̀ yàtọ̀ sí ara wọn. Níwọ̀n ìgbà tí ó ti jẹ́ pé odidi gbólóhùn ni a óò máa ṣe àwítúnwí wọn, ó gbọ́dọ̀ ní ìtumọ̀. A lè rí àwítúnwí odidi gbólóhùn tí yóò ju ẹyọ̀kan ṣoṣo lọ nínú afọ̀ kan náà. Bí a bá ti ń rí i ní ìlà bíi méjì sí mẹ́rin, a óò ti mọ̀ pé irúfẹ́ gbólóhùn bẹ́ẹ̀ ni òpómúléró fún afọ̀ náà. Àpẹẹrẹ àwítúnwí odidi gbólóhùn ni a rí nínú orin Àjàgbó ìsàlẹ̀ yìí:







**Èka-Èdè Ọ̀gbàgì**

Èlé: Ùdọ̀bálẹ̀ í ṣùà
Mìí yá kí Gbàdà jẹ́ ni relé Ọba
Ke yá ro tẹrun rẹ̀
Ojú olè rèé!
Ègbè: Oolè è è
Èlé: Ojú olè rèé!
Ègbè: Oolè è è
Èlé: Ìhin ẹlẹgbẹ́ mi
Ẹ̀ mọmọ̀ ṣolè bíi ti Gbàdà
Ẹ̀ mọmọ̀ kọ́ṣẹ́kúṣẹ́ nọ́họ́ Gbàdà
Uhun kojú olè í rí mọ̀ í suhàn.

**Yorùbá Àjùmọ̀lò**

Èlé: Ìdọ̀bálẹ̀ kì í ṣèwà
Mo wá ní kí Gbàdà jẹ́ a lọlé Ọba
Kó lọ ro tẹnu rẹ̀ ẹ̀
Ojú olè rèé!
Ègbè: Oolè è è
Èlé: Ojú olè rèé!
Ègbè: Oolè è è
Èlé: Ẹ̀yin akẹgbẹ́ mi
Ẹ má ṣolè bíi ti Gbàdà
Ẹ má kọ́ṣẹ́kúṣẹ́ lọ́wọ́ Gbàdà
Ohun tí ojú olè ń rí kì í dára.

(Àsomọ́ II, ìlà 14-24)

Ní ìlà kẹtàdínlógún àti ìlà kọkàndínlógún ni àwítúnwí odidi gbólóhùn yìí ti wáyé. Wọ́n bú Gbàdà níbẹ̀ lórí iṣu tó jí wà nínú oko olóko. Àwọn gbólóhùn náà dúró bí orin èébú, àbùkù ni wọ́n sì fi èyí ṣe fún un, kí ó ba à lè jáwọ́ nínú ìwà olè àti kí ìṣẹ̀lẹ̀ náà lè jẹ́ ẹ̀kọ́ fún àwọn ènìyàn tí wọ́n ní irúfẹ́ ìwà bẹ́ẹ̀ lọ́kàn láti hù. Ẹwẹ, nínú ìlà méjì yìí, wọ́n gbé Gbàdà kalẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ẹ̀dá-ìtàn tí wọ́n fi ṣẹ̀fẹ̀ bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ó mú àbùkù lọ́wọ́. Àpẹẹrẹ mìíràn tí a tún rí nínú orin Àjàgbó yìí ni:

**Èka-Èdè Ọ̀gbàgì**

Èlé: Ọmọ Ajúta a a
Ọmọ Ajúta a a
Ṣẹ́ ẹ̀ẹ́ mọhun kó ṣẹlẹ̀
Nípa ọ̀gá rin kọ̀n
Kó jólóyè núlùú?

**Yorùbá Àjùmọ̀lò**

Èlé: Ọmọ Ajúta a a
Ọmọ Ajúta a a
Ṣé ẹ mohun tó ṣẹlẹ̀
Nípa ọ̀gá yín kan
Tó jólóyè nínú ìlú?

Ó wùwà ké sunhọ̀n
Ọ̀gá a tíṣà kọ̀n
Ní ṣùkúrù Ajúta
Hàà! Ní ṣùkúrù Ajúta
Nó ti mọ́mọ mábẹ́ igi ọ̀pẹ̀
Kó ké e yáa gbà nábẹ́
Ó bòbò jẹ ò ó bòbò jẹ
Chief Kórewọ̀lú bòbò jẹ
Ègbè: Ó bòbò jẹ ò ó bòbò jẹ
Chief Kórewọ̀lú bòbò jẹ.

Ó hùwà tí ò dára
Ọ̀gá a tíṣà kan
Ní ṣùkúrù Ajúta
Háà! Ní ṣùkúrù Ajúta
Ló ti mú ọmọ mábẹ́ igi ọ̀pẹ
Tó ń bá a ní àjọṣepọ̀
Ó bòbò jẹ ò ó bòbò jẹ
Chief Kórewọ̀lú bòbò jẹ
Ègbè: Ó bòbò jẹ ò ó bòbò jẹ
Chief Kórewọ̀lú bòbò jẹ.

(Àsomọ̀ IV, ìlà 1-15)

Ìlà kìn-ín-ní àti ìkejì ni ìtẹnumọ́ odidi gbólóhùn ti wáyé nínú àpẹẹrẹ òkè yìí. Ọgbọ́n ìtẹnumọ́ ọ̀gangan-ipò ibi tí Chief Kórewọ̀lú ti bá ọ̀kan lára àwọn akẹ́kọ̀ọ́ rẹ̀ ní àjọṣepọ̀ ni ọ̀kọrin ń fọ́gbọ́n sọ níbẹ̀ láti ta àwọn olùgbọ́ rẹ̀ lólobó ibi gan-an tí Kórewọ̀lú ti hùwà ìbàjẹ́ yìí. Nínú ìlà kẹtàlá àti ìlà karùndínlógún, apohùn ṣíṣọ lójú ẹni tó hùwà àgbèrè nínú àyọlò òkè yìí. "Chief Kórewọ̀lú" tí ó bá akẹ́kọ̀ọ́ rẹ̀ lájọṣepọ̀ ni ọ̀kọrin ń jẹ́ ká mọ̀. Erin kì í jẹko abẹ́ rẹ̀ ni Yorùbá wí ṣùgbọ́n kì í ṣe láyé òde-òní.

## Àwítúnwí Àkùdé Gbólóhùn

Gbólóhùn ni a lè pè ní ìpèdè kíkún tí ó ní ìtumọ̀, tí ó sì máa ń ní abala kókó-gbólóhùn nínú. Ìhun gbólóhùn tí a kò bá rí kókó-gbólóhùn nínú ìhun rẹ̀, àkùdé gbólóhùn ni. Àkùdé gbólóhùn túmọ̀ sí abala odidi ìhun gbólóhùn kan ṣoṣo. Irúfẹ́ gbólóhùn yìí máa ń jẹ́ afarahẹ́. Ẹ jẹ́ á wo àpẹẹrẹ orin Àjàgbó ìsàlẹ̀ yìí:

**Èka-Èdè Ọ̀gbàgì**

Ó kóbò í ṣuṣu ẹ̀mùẹ̀
Kọ̀ í jẹ nẹ́rẹ̀ kọ̀n nọ́dún
Ọ̀rọ̀ òrúnrùn nèí nẹ́run àgbà ùyà
Kò bá ti náya ko mójú tó o
Kò bá ti nọ́mọ ko mójú tó o
É ì ṣẹ̀mùẹ̀ é ì ṣẹ̀mùẹ̀
Òbò Rálìátù mọ̀ í ṣẹ̀mùẹ̀
Ègbè: Òbò rẹ̀ mọ̀ í ṣẹ̀mùẹ̀ ẹ̀
Èlé: Ṣẹ̀mùẹ̀ ṣẹmuẹ
Ṣẹ̀mùẹ̀ ṣẹmuẹ
Òbò mọ̀ í ṣẹ̀mùẹ̀
Ègbè: Òbò mọ̀ í ṣẹ̀mùẹ̀ ẹ̀.

**Yorùbá Àjùmọ̀lò**

Ó lóbò kì í ṣẹṣu ẹ̀mùẹ̀
Tí wọ́n ń jẹ nígbà kan
lọ́dún
Ọ̀rọ̀ òórùn nìyí lẹ́nu àgbààyà
Bí o bá ti láya kí o bójú tó o
To bá ti lọ́mọ ko bójú tó o
Kì í ṣẹ̀mùẹ̀ kì í ṣẹ̀mùẹ̀
Òbò Rálìátù kì í ṣẹ̀mùẹ̀
Ègbè: Òbò rẹ̀ kì í ṣẹ̀mùẹ̀ ẹ̀
Èlé: Ṣẹ̀mùẹ̀ ṣẹmuẹ
Ṣẹ̀mùẹ̀ ṣẹmuẹ
Òbò kì í ṣẹ̀mùẹ̀
Ègbè: Òbò kì í ṣẹ̀mùẹ̀ ẹ̀.

(Àsomọ̀ I, ìlà 1-12)

Abala odidi gbólóhùn: "ko bójú tó o", tí ó wà ní ìlà kẹrin àti karùn-ún nínú àyọlò òkè yìí kò ní ìtumọ̀ kíkún, àbọ̀ ò lè ṣe iṣẹ́ odidi, èyí ló fà á tí "ko bójú tó o" kò fi lè fún wa ní ìtumọ̀ kíkún níbẹ̀. Ìkìlọ̀ ni ọ̀kọrin fi àwọn ìlà náà ṣe fún àwọn ènìyàn, pé kí wọ́n bójú tó ìyàwó àti ọmọ wọn obìnrin, kí ó má di pé àwọn oníṣekúṣe bá wọn sùn láìròtẹ́lẹ̀. Ìpèsákiyèsí ni ìlà méjì yìí jẹ́ fún gbogbo àwọn olùwòran eré Àjàgbó lágbo eré, ṣùgbọ́n àìsí ìtumọ̀ kíkún fún àwọn àkùdé ìlà wọ̀nyí ni ò jẹ́ kí wọ́n gbé ìtumọ̀ yọ. Àpẹẹrẹ mìíràn tí a tún rí nínú orin Àjàgbó yìí ni:

**Èka-Èdè Ọ̀gbàgì**

Baba kéè súnhun kọ̀nkọ̀n
Pé ìyọn ìyálé un mọ̀ ṣọ̀nìyọ̀n
Mìí fẹ́ Baba tọ́n nùjà bẹ̀rẹ̀
Mìí fẹ́ Baba tọ́n nasọ̀ bé yọ

**Yorùbá Àjùmọ̀lò**

Baba ní kò sí wàhálà
Pé àwọn ìyálé òun ṣènìyàn
Mo fẹ́ Baba tán nìjà bẹ̀rẹ̀
Mo fẹ́ Baba tán lasọ̀ bé yọ

| | |
|---|---|
| Oko kòkó nó fùjà | Oko kòkó ló fàjà |
| Ọ̀ ọ́ kúhun kí nálẹ̀ ké tó ó pín | Wọn lóhun tó wà nílẹ̀ tí ò tó ó pín |
| Nì mí yá jòkó tì | Ni mo wá jókòó tì |
| Ùjà bẹ̀rẹ̀ | Ìjà bẹ̀rẹ̀ |
| Asọ̀ bẹ̀rẹ̀ | Asọ̀ bẹ̀rẹ̀ |
| Kiní mi tutùù | Kiní mi tutùù |
| Kiní mi tutu. | Kiní mi tutùù. |

(Àsomọ́ III, ìlà 1-11)

Ọ̀kọrin Àjàgbó lo àwítúnwí àkùdé gbólóhùn ní ìlà kẹta àti ìlà kẹrin. "Mìí fẹ́ Baba tọ́n" ni orin òkè yìí fi hàn gẹ́gẹ́ bí ẹjọ́ tí obìnrin tí wọ́n da omi ata sójú-ara rẹ̀ rò nígbà tó ń wí làbárè bí ọ̀ràn ṣe rìn. Àìkún gbólóhùn náà ni ò jẹ́ ká rí ìtumọ̀ ohun tí ọ̀kọrin ní lọ́kàn gan-an ní pàtó. Ọ̀rọ̀ wá dà bí ìgbà tí a gé orí nù tí ó ku kìkì ara.

Àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tí wọ́n jẹ yọ nínú àwọn àpẹẹrẹ àwítúnwí gbólóhùn tí a ṣàlàyé sókè yìí ń fi ìmọ̀ ìjìnlẹ̀-èrò àti ìgbàgbọ́ àwọn ènìyàn ìlú Ọ̀gbàgì-Àkókó hàn nípa ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ wọn, gẹ́gẹ́ bí ó ti ṣe ń hàn láwùjọ Yorùbá. Èrò wọn ni pé, ó di dandan kí àwọn ṣe àṣeyọrí lórí fífí rán ènìyàn létí ohun tí àwọn oníṣẹ́ láabi ń dánwò láwùjọ, gẹ́gẹ́ bí ó ti hàn nínú àwọn àyọlò orin Àjàgbó okè wọ̀nyí. Èyí wà lára àfojúsùn àwọn agbátẹ̀rù tíọ́rì ìfojú-ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbépọ̀-wo lítíréṣọ̀ tí a lò.

**Ìbéèrè-pèsìjẹ**

Ìbéèrè-pèsìjẹ ni ìbéèrè tí òǹkọ̀wé, akéwì tàbí ọ̀kọrin bèèrè léyìí tí kò retí ìdáhùn láti ọ̀dọ̀ ẹnìkankan. Àwọn akéwì a máa lo ọnà-èdè yìí láti fìdíí kókó ọ̀rọ̀ múlẹ̀. Ẹ wo àpẹẹrẹ orin Àjàgbó ìsàlẹ̀ yìí:

| **Èka-Èdè Ọ̀gbàgì** | **Yorùbá Àjùmọ̀lò** |
|---|---|
| Èlé: Mìí dè ti dé | Èlé: Mo tún tí dé |
| Pẹ̀lú tuntun | Pẹ̀lú titun |





| | |
|---|---|
| Kàrẹṣẹ̀ kí í núṣẹ̀ àgbẹ̀? | Ẹ̀ṣẹ̀ wo ló wà nínú iṣẹ́ àgbẹ̀? |
| Kahun kó le núṣẹ́ oko? | Kín ló le nínú iṣẹ́ oko? |
| Bẹ́ẹ̀ uṣẹ́ àgbẹ̀ | Bẹ́ẹ̀ iṣẹ́ àgbẹ̀ |
| Nuṣẹ́ alẹ̀ ra | Niṣẹ́ ilẹ̀ wa |
| Ọni ké ṣuṣẹ́ | Ẹni tí ò ṣiṣẹ́ |
| Á mọ̀ jalè o o | Á mà jalè o o |
| Gbàdà mádàá ràlà oko | Gbàdà mádàá lọ sí oko |
| Éè mú ṣánko. | Kò fi gé oko |
| Uṣẹ́ olè nó mú í ṣe | Iṣẹ́ olè ló fi ń ṣe |
| É í ṣùà | Kì í ṣèwà |
| Ègbè: Ùdọ̀bálẹ̀ í ṣùà | Ègbè: Ìdọ̀bálẹ̀ kì í ṣèwà |

(Àsomọ́ II, ìlà 1-13)

Gbólóhùn tí ó wà ní ìlà kẹta àti kẹrin ni apohùn fi béèrè ọ̀rọ̀ lọ́wọ́ àwọn ènìyàn tó ń wo eré Àjàgbó. Ohun tó nira níbi iṣẹ́ àgbẹ̀, tí Gbàdà ò fi lè lọ dá oko tirẹ̀, tó fi jẹ́ iṣu ẹgbẹ́ rẹ̀ ló lọ ń jí wà ni ọ̀kọrin ń béèrè nínú gbólóhùn méjèèjì náà. Apohùn kò retí èsì láti ọ̀dọ̀ àwọn òǹwòran, ó kàn ń fi ìbéèrè náà pe ọkàn wọn papọ̀ síbi ọ̀dọ̀ rẹ̀ ni, kí wọ́n lè gbọ́ ohun tó mú kí ó béèrè ìbéèrè náà. Àpẹẹrẹ mìíràn tí a tún rí nínú orin Àjàgbó yìí ni:

| **Èka-Èdè Ọ̀gbàgì** | **Yorùbá Àjùmọ̀lò** |
|---|---|
| Èlé: Ó kọ́mọ Jésù mọ̀ í bỌ̀gún | Èlé: Ó lọ́mọ Jésù kì í bỌ̀gún |
| Ègbè: Mìí dè gbọ́ tuntun | Ègbè: Mo tún gbọ́ titun |
| Jésù nOlùgbàlà Ọba ra | Jésù lOlùgbàlà Ọba wa |
| Ọ̀rọ̀n mọ̀ nèí irá Ọ̀gbàgì | Ọ̀ràn mà nìyí ará ìlú Ọ̀gbàgì |
| Kahun ka ná ṣèí sí ò lẹ́gbẹ́mi? | Kí la fẹ́ ṣèyí sí o akẹgbẹ́ mi? |

(Àsomọ́ V, ìlà 11-15)

*Ondo Journal of Arts, Faculty of Arts, Adeyemi Federal University of Education, Ondo. Vol. 2. No. 1&2, 2026* | Àgbéyẹ̀wò Ìṣọwọ́lò-Èdè Inú Orin Àjàgbó ní Ọ̀gbàgì-Àkókó

Ìlà karùndínlógún tó parí orin òkè yìí ni gbólóhùn aṣèbéèrè ti wáyé. Gbogbo rògbòdìyàn bí Ọba ṣe sá kúrò láàrin ìlú ni ọ̀kọrin àti àwọn elégbè rẹ̀ fi ń bèèrè ìbéèrè lọ́wọ́ ara wọn pé, kí ni ará ìlú Ọ̀gbàgì-Àkókó ti fẹ́ ṣe ìṣẹ̀lẹ̀ náà sí?

Àwòrán àwùjọ hàn nínú àwọn àyọlò orin òkè yìí. Inú àwùjọ ni aráàlú ti ń ja olè, tí ọba ti máa ń kọ ọ̀rọ̀ sí ìlú lẹ́nu, tí yóò sì ṣe ifẹ́ inú rẹ̀. Bákan náà, inú àwùjọ ni a ti ń rí ọba ti yóò máa tàpá sí àṣà àti ìṣẹ̀ṣe Yorùbá. Èyí ló bí ìdí tí a fi ṣàmúlò tíọ́rì soṣiọ́lọ́jì tí a lò, nítorí ìṣẹ̀lẹ̀ inú àwùjọ ni àfojúsùn àwọn olùdásílẹ̀ tíọ́rì náà.

**Àfiwé**

Àfiwé ni fífi ohun tí a mọ̀ ṣàlàyé ohun tí a kò mọ̀ tàbí ohun tí ìtumọ̀ rẹ̀ farasin, (Adéọ̀ṣun, 2016). Ìṣàfiwé nǹkan méjì láti jẹ́ kí ohun tí a ń sọ ní ìtumọ̀ ìjìnlẹ̀ ló máa ń bí ká fi nǹkan méjì wéra wọn yálà àfiwé tààrà tó lọ sàn-án tàbí àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ̀ tí kò lọ geerege ni onímọ̀ yìí ń ṣàlàyé. Ọ̀nà ì-bu-ẹwà kún iṣẹ́-ọnà aláwòmọ́-lítíréṣọ̀ ni pàtàkì iṣẹ́ tí ó ń ṣe.

**Àfiwé Tààrà**

Èyí ni fífi ohun kan wé ohun mìíràn tàbí fífi ènìyàn wé ènìyàn mìíràn lọ́nà tààrà. Ọlátúnjí (1984:53) sọ pé; "A simile is an overt comparison. It describes one object as being similar to another". (Àfiwé tààrà jẹ́ ìṣàfiwé nǹkan méjì lọ́nà tí kò rújú rárá. Ó máa ń ṣàpèjúwe nǹkan láti fi ṣàfiwé, tàbí àfijọ rẹ̀ tàbí láti fi ṣe déédé pèlú nǹkan mìíràn). Ìtumọ̀ èyí ni fífi ohun kan wé ohun kejì, tí ọ̀nà tí ìṣàfiwé wọn yóò gbà wáyé kò fi ní lọ́jú pọ̀ rárá. Ẹ jẹ́ á wo àpẹẹrẹ orin Àjàgbó tí a yọ lò sí ìsàlẹ̀ yìí:

| **Èka-Èdè Ọ̀gbàgì** | **Yorùbá Àjùmọ̀lò** |
|---|---|
| Ojú olè rèé! | Ojú olè rèé! |
| Ègbè: Oolè è è | Ègbè: Oolè è è |
| Èlé: Ojú olè rèé! | Èlé: Ojú olè rèé! |
| Ègbè: Oolè è è | Ègbè: Oolè è è |
| Èlé: Ìhin ẹlẹgbẹ́ mi | Èlé: Ẹ̀yin akẹgbẹ́ mi |
| Ẹ̀ mọmọ̀ ṣolè bíi ti Gbàdà | Ẹ má ṣolè bíi ti Gbàdà |
| Ẹ̀ mọmọ̀ kọ́ṣẹ́kúṣẹ́ nóhọ́ Gbàdà | Ẹ má kọ́ṣẹ́kíṣẹ́ lọ́wọ́ Gbàdà |
| Uhun kojú olè í rí mọ̀ í suhàn. | Ohun tí ojú olè ń rí kì í dára. |

(Àsomọ́ II, ìlà 25-32)

Ọ̀kọrin fi Gbàdà wé olè tí ó máa ń jí ohun olóhun ní ìlà kọkànlélọ́gbọ̀n. Ìdí ni pé, gbogbo ìwà ojúkòkòrò tó kún ojú àti ọwọ́ olè náà ló kún ti Gbàdà. Èyí ló wá mú kí ọ̀kọrin máa kìlọ̀ fún àwọn òǹwòran rẹ̀ pé kí wọ́n má hùwà bíi ti Gbàdà, pé kí wọ́n má ṣe ní ìbáṣepọ̀ kankan pẹ̀lú Gbàdà, kí ó má lọ kọ́ wọn níṣẹ́ olè tàbí kó bá wọn. Àpẹẹrẹ mìíràn tí a tún rí nínú orin Àjàgbó yìí ni:

| **Èka-Èdè Ọ̀gbàgì** | **Yorùbá Àjùmọ̀lò** |
|---|---|
| Èlé: Oge ọ̀rọ̀n | Èlé: Oge ọ̀ràn |
| Oge àbùkù | Oge àbùkù |
| Ó dúdú nẹ́ṣẹ̀ ẹ̀ | Ó dúdú lẹ́ṣẹ̀ ẹ̀ |
| Ó pupa nọ́ra a | Ó pupa lára a |
| Ọra dọra fáńtà à | Ara dara fáńtà à |
| Ọra dọra kókì ì | Ara dara kóòkì |
| Àhọ̀ dà bíi ti kàlákìní ò ò ò | Àwọ̀ dà bíi ti kàlákìnní ò ò ò |
| Onúyà ni Bọ́ṣẹ̀ ẹ̀ | Oníyà ni Bọ́ṣẹ̀ ẹ̀ |
| Eléṣì ni yèyé Búkì ì | Alábùkù ni ìyá Búkì ì |
| Ó ṣádé orí rẹ̀ nù | Ó ṣádé orí rẹ̀ dànù |
| Ó kọ̀yìn sọ́là a rẹ̀. | Ó kẹ̀yìn sọ́là a rẹ̀ |

(Àsomọ́ VI, ìlà 1-11)

Ní ìlà keje, ọ̀kọrin fi àwọ̀ ara obìnrin wé àwọ̀ kàlákìnní tó túmọ̀ sí kí nǹkan ní oríṣìíríṣìí àwọ̀ tó ń rí ràkọ̀ràkọ̀. Ohun tí ọ̀kọrin ń ṣe lálàyé ni pé, nípa lílo àwọn ohun-ìpara ayé òde-òní, tí ó ti kún fún oríṣìíríṣìí kẹ́míkà líle, tí àwọn ọmọge wa ń lò, ń jẹ́ kí àwọ̀ ara wọn rí bálabàla. Apá kan á dúdú, apá kan á pupa bíi kóòkì àti fáǹtà.

**Àfiwé Ẹlẹ́lọ̀ọ́**

Àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ ni àfiwé tó jẹ́ pé ìtumọ̀ tó farasin ni wọ́n máa ń fún wa. Inú àfiwé yìí ni a tí máa ń fi nǹkan méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ wéra lọ́nà ẹ̀rọ. Nínú àfiwé yìí, ṣe ni a máa ń gbé àbùdá ohun kan wọ òmíràn láti máa hùwà tàbí ṣe bí irúfẹ́ nǹkan náà. Àpẹẹrẹ èyí náà ni a rí nínú orin Àjàgbó ìsàlẹ̀ yìí:

| **Èka-Èdè Ọ̀gbàgì** | **Yorùbá Àjùmọ̀lò** |
|---|---|
| Ó pupa nọ́ra a | Ó pupa lára a |
| Ọra dọra fáǹtà à | Ara dara fáǹtà à |
| Ọra dọra kókì ì | Ara dara kókì ì |
| Àhọ̀ dà bíi ti kàlákìní ò ò ò | Àwọ̀ dà bíi ti kàlákìní ò ò ò |
| Onúyà ni Bọ́sẹ̀ ẹ̀ | Oníyà ni Bósẹ̀ ẹ̀ |
| Eléṣì ni yèyé Búkì ì | Alábùkù ni ìyá Búkì ì |
| Ó ṣádé orí rẹ̀ nù | Ó ṣádé orí rẹ̀ dànù |
| Ó kọ̀yìn sọ́là a rẹ̀. | Ó kẹ̀yìn sọ́là a rẹ̀ |

(Àsomọ́ VI, ìlà 4-11)

Ní ìlà kẹjọ àti ìlà kesàn-án ni ọ̀kọrin tí ṣàmúlò àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́. Ó ní "Onúyà ni Bọ́sẹ̀ ẹ̀" àti "eléṣì ni yèyé Búkì ì". Gbogbo ẹni tí kò bá ti ní ìtìjú, tí ó máa ń ṣàgbèrè kiri ìgboro, tí ó ń fẹ̀yìn ralẹ̀ fún gbogbo ọkùnrin tó bá rí, ni àwọn aráàlú Ọ̀gbàgì-Àkókó máa ń pè ní "ẹnúyà" (ẹni ìyà) àti "eléṣì" (ẹni àbùkù). Èyí ló fà á tí wọ́n fi pe Bọ́sẹ̀ tó jẹ́ ìyá Búkì ní "Onúyà" àti "Eléṣì". Àpẹẹrẹ àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ mìíràn tí a tún rí nínú orin Àjàgbó yìí ni:





| **Èka-Èdè Ọ̀gbàgì** | **Yorùbá Àjùmọ̀lò** |
|---|---|
| Èlé: Nálalẹ́ nọ̀ í wó o | Èlé: Lálalẹ́ ni wọ́n ń wó o |
| Nágo mẹ́sàn-án nẹ́gbẹ̀ẹ́ ulé iye ọba | Láago mẹ́sàn-án lẹ́gbẹ̀ẹ́ ilé ìyá ọba |
| Ègbè: Ìrì wọ̀wọ̀ ọ̀ | Ègbè: Ìrì wọ̀wọ̀ ọ̀ |
| Èlé: Gèlè obùnrin-in | Èlé: Gèlè obìnrin-in |
| Gèlè obùnrin mọ̀ dàmútẹ́ ò e e | Gèlè obìnrin mà dàmútẹ̀ ò e e |
| Irá ulé iye ọba kẹ́ẹ̀ í hò? | Olùgbé ilé ìyá ọba kí lẹ̀ ń wò? |
| Ègbè: Uṣẹ́ lílá í nẹ́gbẹ̀ẹ́ ulé rin | Ègbè: Iṣẹ́ ńlá wà lẹ́gbẹ̀ẹ́ ilé yín |
| Èlé: Ọ̀ ọ́ sẹ̀gbẹ́ ulé iye ọba di hòtẹ́ẹ̀lì | Èlé: Wọ́n sẹ̀gbẹ́ ilé ìyá ọba di hòtẹ́ẹ̀lì |
| Kọ̀ ọ́ málalẹ́ í nọ́. | Tí wọ́n ń falaalẹ́ ná. |

(Àsomọ́ VII, ìlà 1-9)

Ní ìlà kejọ, ọ̀kọrin pe ilé ìyá ọba ní ilé ìtura. Ó jẹ́ kó yé wa pé ojoojúmọ́ ni àwọn olólùfẹ́ ìkọ̀kọ̀ méjì inú orin òkè yìí máa ń lo ẹ̀gbẹ́ ilé náà láti máa bára wọn lájọṣepọ̀. Alaalẹ́ tí ẹnikẹ́ni ò ní lè rí wọn ni ọ̀kọrin ní àwọn alágbèrè méjèèjì yìí máa ń pàdé níbẹ̀. Níwọ̀n ìgbà tó sẹ́ pé gbogbo àbùdá tí a lè rí mọ́ ààyè kan, tí a fi lè pè é ní ilé-ìtura ni ọ̀kọrin rí lára ọ̀gangan-ipò ibi tí alágbèrè inú àyọlò òkè wọ̀nyí ti máa ń rira wọn, ìdí nìyí tí ọ̀kọrin fi ṣe ìfiwéra náà bẹ́ẹ̀.

Gbogbo àwọn àkóónú tó fara hàn nínú àwọn àyọlò tí a ṣàlàyé lókè yìí ló kún inú àwùjọ wa lónìí. Èyí ló mú wa yan tíọ̀rì sọṣiọ́lọ́jì láti ṣe ìtupalẹ̀ yìí.

**Àkànlò-Èdè**

Àkànlò-èdè ni ìpèdè tí ìtumọ̀ rẹ̀ farasin. Ẹni tó bá gbọ́ èdè yé ni ó lè sọ ìtumọ̀ tí irúfẹ́ ìpèdè bẹ́ẹ̀ ní. A kò lè ti ara àwọn ọ̀rọ̀ tó jẹ́ àkóónú ìpèdè tàbí gbólóhùn náà mọ ìtumọ̀ rẹ̀ àyàfi bí a bá sún mọ́ àwọn àgbà tí ó gbọ́ èdè yé dáadáa. Ẹ wo àpẹẹrẹ èyí nínú orin Àjàgbó ìsàlẹ̀ yìí:

**Èka-Èdè Ọ̀gbàgì**

Èlé: À! Ọ̀mẹ̀nẹ̀kẹ̀n, mí dè ṣe
Gbọkọ ọlọ́kọ rè, Ọ̀mẹ̀nẹ̀kẹ̀n
Ẹ̀gbè: Ṣé í pani ni kó dè ṣe?
Èlé: Okó jọkó yá bọ́kọ̀ rẹ̀
Ẹ̀gbè: Ṣé í pani ni kó dè ṣe?
Èlé: Ojú aṣẹ́hó gbébe kọ̀n irá mi kete
Ùka kọ̀n í gbùdí alágbèrè rọn.

**Yorùbá Àjùmọ̀lò**

Èlé: À! Ọ̀mẹ̀nẹ̀kẹ̀n, mi ò ṣe
Fi ọkọ ọlọ́kọ sílẹ̀, Ọ̀mẹ̀nẹ̀kẹ̀n
Ẹ̀gbè: Ṣé ó ń pani ni tí o ò tún fi ṣe?
Èlé: Ọkọ jọkọ lọ bọ́kọ̀ọ̀ rẹ
Ẹ̀gbè: Ṣé ó ń pani ni tí o ò fi ṣe mọ́?
Èlé: Ojú aṣẹ́wó ò gbébi kan ènìyàn gbogbo
Ìka kan kì í wọ̀dí alágbèrè wọn.

(Àsomọ́ VIII, ìlà 1-7)

Ní ìlà kẹfà, wọ́n lo àkànlò-edè "aṣẹ́hó" láti ṣàlàyé irúfẹ́ ènìyàn tí Ọ̀mẹ̀nẹ̀kẹ̀n jẹ́. Ìtumọ̀ tí àkànlò-edè yìí ní ni alágbèrè tàbí olówò-nàbì. Wọ́n lo ọ̀rọ̀ "aṣẹ́hó" yìí láti mú kí ìṣẹ̀lẹ̀ tí wọ́n ń bá bọ̀ ní ìgbádùn ajẹmẹ́wà; kí wọ́n lè mọ ẹni tí ó gbédè dáadáa. Ẹni tí kò gbédè lè rò pé ẹni tí ó máa ń bá ènìyàn ṣe pàṣípààrọ̀ owó ni ọ̀kọrin ń sọ láìmọ̀ pé alágbèrè ló ní lọ́kàn. Ẹ jẹ́ á tún wo àpẹẹrẹ àkànlò-èdè mìíràn nínú orin Àjàgbó ìsàlẹ̀ yìí:

**Èka-Èdè Ọ̀gbàgì**

Onúyà ni Bọ́sẹ̀ẹ̀
Eléṣì ni yèyé Búkì ì
Ó ṣádé-orí rẹ̀ nù
Ó kọ̀yìn sọ́là a rẹ̀
Irá ulé mọ̀ tẹ́rìrà
Nójú ìyàó eléṣì.

**Yorùbá Àjùmọ̀lò**

Oníyà ni Bósẹ̀ ẹ̀
Alábùkù ni ìyá Búkì ì
Ó ṣádé-orí rẹ̀ dànù
Ó kẹ̀yìn sọ́là a rẹ̀
Ara ilé mà téèrà
Lójú ìyàwó alábùkù.

(Àsomọ́ VI, 8-13)

Ìlà kẹwàá inú orin òkè yìí ni àpẹẹrẹ àkànlò-èdè níbẹ̀. Ọ̀kọrin fi ń yé wa pé Bọ́sẹ̀ ò bọ̀wọ̀ fún ọkọ rẹ̀, pé ṣe ni ó ń tojú bọ ilé ọkùnrin mìíràn tí ó ń yàn ní àlè. Ọ̀kọrin wá fi ń yé wa pe, ọkọ ni olówó ori ìyàwó rẹ̀, pé ó yẹ kí ìyàwó máa pọ́n ọkọ rẹ̀ lé. Ọkọ tún ni aláàbò fún ìyàwó nígbà tí wàhálà kan bá ṣẹlẹ̀ nínú ilé. Bí Bọsẹ̀ ò ṣe bọ̀wọ̀ fún ọkọ rẹ̀; tí ó ń dọrẹ̀ẹ́ ìkọ̀kọ̀ lẹ́yìn ọkọ rẹ̀ ni àkanlò-èdè òkè yìí ń ṣe ní







àlàyé. Ara ìṣẹ̀lẹ̀ ìwà ìbàjẹ́ àwùjọ ni tíọ́rì ìfojú-ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbépọ̀-wo lítíréṣọ̀ tí a lò fún iṣẹ́ ìwádìí yìí ń ṣàlàyé nìyí.

**Àyálò Èdè**

Àyálò èdè jẹ́ ọ̀nà kan tí à ń gbà yá ọ̀rọ̀ wọnú èdè Yorùbá láti inú àwọn èdè mìíràn. Ìlú Ọ̀gbágí-Àkókó tí iṣẹ́ ìwádìí yìí ti wáyé jẹ́ ìlú tí onírúurú ẹ̀yà ènìyàn ń gbé. Nípa báyìí, èdè ẹnu wọn ti wá ohun tọ́pọ̀ ọmọ ìlú Ọ̀gbágí-Àkókó ń mọ̀ bí wọ́n ṣe ń gbọ́ èdè náà, ìmọ̀ mọ̀-ọ́n-kọ mọ̀-ọ́n-kà náà sì mú kí ó rọrùn fún wọn. Èyí ló bí àsáwọ̀ oríṣìí èdè mìíràn tó ń jẹ yọ nínú orin Àjàgbó tí wọ́n ń kọ. Ẹ wo àpẹẹrẹ orin Àjàgbó ìsàlẹ̀ yìí:

**Èka-Èdè Ọ̀gbàgì**

Èlé: Ìwòí ẹ̀ṣí
NỌba ria sá lọ
Ẹ̀gbè: Ó sá lọ
Èlé: É dúró bỌ̀gún
Kárùn rá lọ tèfètèfè
Kọ̀lọ̀kadà mọ́ ṣubú nórí títì
Kónímọ̀tò mọ́ ṣubú nórí títì
Kí ásídẹ́ntì mọ́ hòlú ra
Ọba ra bá họ
Ẹ̀gbè: Háà, ó sá lọ
Èlé: Ó kọ́mọ Jésù mọ̀ í bỌ̀gún.

**Yorùbá Àjùmọ̀lò**

Èlé: Ìwòyí ọdún tí ó kọjá
Ni Ọba wa sá lọ
Ẹ̀gbè: Ó sá lọ
Èlé: Kò dúró bọ Ògún
Kárùn rá lọ tèfètèfè
Kọ̀lọ̀kadà má ṣubú lórí títì
Kónímọ̀tò má ṣubú lórí títì
Kí ásídẹ́ntì má wọ̀lú wa
Ọba wa bá họ
Ẹ̀gbè: Háà, ó sá lọ
Èlé: Ó lọ́mọ Jésù kì í bỌ̀gún

(Àsomọ́ V, ìlà 1-11)

Ní ìlà keje, wọ́n yá ọ̀rọ̀ "-mọ́tò" láti inú èdè Gẹ̀ẹ́sì, ọ̀kọrin tún yá "ásídẹ́ntì" lò ní ìlà kẹjọ láti inú èdè Gẹ̀ẹ́sì nípa ìlànà ìfetíyá. Síwájú sí i, ní ìlà kọkànlá, "Jésù" tí ojúlówó kíkọ rẹ̀ jẹ́ "Jesus" ni ọ̀kọrin yá lò láti inú èdè Jew. Akitiyan ìmúgbóòrò èdè ni yíyá ọ̀rọ̀ láti inú èdè

kan wọnú èdè Yorùbá. Àpẹẹrẹ mìíràn tún nìyí ní ìsàlẹ̀ láti inú orin Àjàgbó:

| **Èka-Èdè Ọ̀gbàgì** | **Yorùbá Àjùmọ̀lọ̀** |
|---|---|
| Èlé: Ọ̀rọ̀ nì mì í bá í bọ̀ kẹ̀ ẹ́ kó pẹ́ mi | Èlé: Ọ̀rọ̀ ni mò ń bá bọ̀ tẹ́ ẹ ló pẹ́ mi |
| Òkété ṣe press up ó ṣe | Òkété ṣe press up ó ṣe |
| Àrà mọ̀ nèí lẹ́gbẹ́ mi | Àrà mà nìyí akẹgbẹ́ mi |
| Ègbè: Mọ́ńdè ṣe press up ó ṣe | Ègbè: Mọ́ńdè ṣe press up ó ṣe |
| Èlé: Mì í dákun ṣíọ́ ariho. | Èlé: Mo rọra dákẹ́ ariwo. |

(Àsomọ́ IX, ìlà 1-5)

Ní ìlà kejì àti ìlà kẹrin, ọ̀kọrin yá ọ̀rọ̀ lò láti inú èdè Gẹ̀ẹ́sì, ó sì lò ó bí elédè ti í lò ó. Irúfẹ́ ẹ̀yà eré ìdárayá kan tó ní í ṣe pẹ̀lú gbígbé ara lọ sókè-sódò ni ọ̀kọrin ń perí níbẹ̀. Ní agbọ́rin tí ọ̀kọrin ti lo. "press up" yìí, ọ̀rọ̀ nípa ìbálòpọ̀ ni ó ń sọ níbẹ̀, láti ṣàlàyé ìwà àgbèrè tí ẹni kan tí ó ń jẹ́ Mọ́ńdè hù pẹ̀lú ọmọdébìnrin kan. Ìwà ìbàjẹ́ yìí wà lára ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ tí ó jẹ àwọn agbátẹrù tíọ́rì sosíọ́lọ́jì tí a mú lò lógún.

| Nọ́ń bà | Orúkọ | Iṣẹ́ | Ọjọ́-Orí | Ìlú | Ọjọ́ |
|---|---|---|---|---|---|
| 1. | Ọ̀kẹ́ Abíọ́dún | Ọ̀kọrin Àjàgbó | 35 | Ọ̀gbàgì-Àkókó | Dec. 20, 2025 |
| 2. | Àbú Ismaila | Ọ̀kọrin Àjàgbó | 54 | Ọ̀gbàgì-Àkókó | Dec. 22, 2025 |
| 3. | Àjàyí Olóyinmọ̀ | Àwòrò | 45 | Ọ̀gbàgì-Àkókó | Dec. 22, 2025 |
| 4. | Jamiu Rachael | Ọ̀kọrin Àjàgbó | 90 | Ọ̀gbàgì-Àkókó | Dec. 22, 2025 |

Kò sí ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn kókó-ọ̀rọ̀ tó jẹ yọ nínú afọ̀ tí a ti ṣàlàyé àyálò èdè lókè yìí tí kò máa fara hàn nínú àwùjọ wa lóníì, bí irúfẹ́ èdè yìí ṣe ń hàn nímú ìsọ̀rọ̀sí àwọn ènìyàn àwùjọ náà ló ṣe hàn nínú orin Àjàgbó tí a ṣàlàyé yìí. Nípa ìdí èyí la ṣe ṣàmúlò tíọ́rì sosíọ́lọ́jì fún ìtúpalẹ̀ tí a ṣe.





**Àgbálọgbábọ̀**

Ọdún Àjàgbó jẹ́ ọdún kan gbòògì tí àwọn ènìyàn ìlú Ọ̀gbàgì-Àkókó fi ń kìlọ̀ ìwà ìbàjẹ́ láwùjọ wọn. Kò sẹ́ni tí wọn kò lè fi orin Àjàgbó bú, ìbáà jẹ́ ọba, ìjòyè tàbí mẹ̀kúnnù láàrin ìlú. Ṣé ẹni tí ó bá wojú ìyàwó ló mọ̀ pé ó ń bínú. Ẹni tí wọ́n bá fi sá (kọrin) Àjàgbó, kò gbọ́dọ̀ bínú débi tí yóò bá àwọn ọ̀kọrin Àjàgbó fa wàhálà. Ọ̀nà bí ọ̀kọrin Àjàgbó ṣe lo èdè nínú orin ọdún Àjàgbó ni a wò nínú iṣẹ́ yìí. Àwọn ìṣọwọ́lò-èdè tí a wò ni àwítúnwí, ìbéèrè-pèsìjẹ, àfiwé, àkànlò-èdè àti àyálò èdè. Ẹ̀wẹ̀, a ṣe àdàkọ àwọn ẹ̀ka-èdè Ọ̀gbàgì tí a fi gba àwọn orin tí a lò nínú iṣẹ́ yìí sí ojúlówó Yorùbá àjùmọ̀lò. Àwọn àmì ohùn tí a lò lórí àwọn ọ̀rọ̀ kan láti inú ẹ̀ka-èdè yàtọ̀ sí àwọn èyí tí a lò nínú Yorùbá àjùmọ̀lò, a sì rí àwọn mìíràn tí wọ́n jọra, ṣùgbọ́n kò sí ìyàtọ̀ ìtumọ̀ kankan nínú àwọn èdè méjèèjì.

Iṣẹ́ ìwádìí yìí fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ìwà ìbàjẹ́ bí àgbèrè ṣíṣe, olè jíjà, ìwà ọ̀lẹ, ìwà ìdojú-àṣà-bolẹ̀, ìwà ojúkòkòrò àti ìwà àìlójútì kò dára. Àwọn ìwà ìbàjẹ́ wọ̀nyí sì ni ọ̀kọrin Àjàgbó máa ń fi ìlò-èdè gbé jáde lọ́nà ẹ̀rọ. Yorùbá kórìíra ìwà ìbàjẹ́ láwùjọ. ìkórìíra yìí ló sì mú kí àwọn ará ìlú Ọ̀gbàgì-Àkókó máa ṣe ọdún Àjàgbó ní ọdọọdún láti máa gbógun ti ìwà ìbàjẹ́ tí ó ń ràn mọ̀mọ̀ nínú ìlú ṇáà. Àwọn ènìyàn ìlú yìí níláti kọ́ ẹ̀kọ́ oníyebíye nínú orin inú ọdún Àjàgbó, kí ìlú náà lè ní ọjọ́ ọ̀la tó dára.

**Àtẹ Abẹ́nà-Ìmọ̀**

**Àkójọ Orin Àjàgbó**

**Àsomọ́ I**

**Èka-Èdè Ọ̀gbàgì**

Ó kóbò í ṣuṣu ẹ̀mùẹ̀
Kọ̀ í jẹ nẹ́rẹ̀ kọ̀n nọ́dún
Ọ̀rọ̀ òrúnrùn nèí nẹ́run àgbà ùyà
Kò bá ti náya ko mójú tó o
Kò bá ti nọ́mọ ko mójú tó o
É ì ṣẹ̀mùẹ̀ é ì ṣẹ̀mùẹ̀
Òbò Ráliàtù mọ̀ í ṣẹ̀mùẹ̀
Ègbè: Òbò rẹ̀ mọ̀ í ṣẹ̀mùẹ̀ ẹ̀
Èlé: Ṣẹ̀mùẹ̀ ṣẹmuẹ
Ṣẹ̀mùẹ̀ ṣẹmuẹ
Òbò mọ̀ í ṣẹ̀mùẹ̀
Ègbè: Òbò mọ̀ í ṣẹ̀mùẹ̀ ẹ̀.

**Yorùbá Àjùmọ̀lò**

Ó lóbò kì í ṣẹṣu ẹ̀mùẹ̀
Tí wọ́n ń jẹ nígbà kan lọ́dún
Ọ̀rọ̀ òórùn nìyí lẹ́nu àgbààyà
Bí o bá ti láya kí o bójú tó o
To bá ti lọ́mọ ko bójú tó o
Kì í ṣẹ̀mùẹ̀ kì í ṣẹ̀mùẹ̀
Òbò Ráliátù kì í ṣẹ̀mùẹ̀
Ègbè: Òbò rẹ̀ kì í ṣẹ̀mùẹ̀ ẹ̀
Èlé: Ṣẹ̀mùẹ̀ ṣẹmuẹ
Ṣẹ̀mùẹ̀ ṣẹmuẹ
Òbò kì í ṣẹ̀mùẹ̀
Ègbè: Òbò kì í ṣẹ̀mùẹ̀ ẹ̀.

**Àsomọ́ II**

**Èka-Èdè Ọ̀gbàgì**

Èlé: Mìí dè ti dé
Pẹ̀lú tuntun
Kàrẹ̀ṣẹ̀ kí í núṣẹ àgbẹ̀?
Kahun kó le núṣẹ́ oko?
Bẹ́ẹ̀ uṣẹ́ àgbẹ̀
Nuṣẹ́ alẹ̀ ra
Ọni ké ṣuṣẹ́
Á mọ̀ jalè o o
Gbàdà mádàá ràlà

**Yorùbá Àjùmọ̀lò**

Èlé: Mo tún tí dé
Pẹ̀lú titun
Ẹ̀ṣẹ̀ wo ló wà nínú iṣẹ́ àgbẹ̀?
Kín ló le nínú iṣẹ́ oko?
Bẹ́ẹ̀ iṣẹ́ àgbẹ̀
Niṣẹ́ ilẹ̀ wa
Ẹni tí ò ṣiṣẹ́
Á mà jalè o o
Gbàdà mádàá lọ sí oko
Kò fi gé oko
Éè mú ṣánko
Uṣẹ́ olè nó mú í ṣe
É í ṣùà
Ègbè: Ùdọ̀bálẹ̀ í ṣùà
Èlé: Ùdọ̀bálẹ̀ í ṣùà
Mìí yá kí Gbàdà jẹ́ ni relé Ọba
Ke yá ro tẹrun rẹ̀
Ojú olè rèé!
Ègbè: Oolè è è
Èlé: Ojú olè rèé!
Ègbè: Oolè è è
Èlé: Ìhin ẹlẹgbẹ́ mi
Ẹ̀ mọmọ̀ ṣolè bíi ti Gbàdà
Ẹ̀ mọmọ̀ kọ̀ṣẹ́kúṣẹ́ nọ́họ́ Gbàdà
Uhun kojú olè í rí mọ̀ í suhàn
Ojú olè rèé!
Ègbè: Oolè è è
Èlé: Ojú olè rèé!
Ègbè: Oolè è è
Èlé: Ìhin ẹlẹgbẹ́ mi
Ẹ̀ mọmọ̀ ṣolè bíi ti Gbàdà
Ẹ̀ mọmọ̀ kọ̀ṣẹ́kúṣẹ́ nọ́họ́ Gbàdà
Uhun kojú olè í rí mọ̀ í suhàn.

Iṣẹ́ olè ló fi ń ṣe
Kì í ṣèwà
Ègbè: Ìdọ̀bálẹ̀ kì í ṣèwà
Èlé: Ìdọ̀bálẹ̀ kì í ṣèwà
Mo wá ní kí Gbàdà jẹ́ a lọlé Ọba
Kó lọ ro tẹnu rẹ̀ ẹ̀
Ojú olè rèé!
Ègbè: Oolè è è
Èlé: Ojú olè rèé!
Ègbè: Oolè è è
Èlé: Ẹ̀yin akẹgbẹ́ mi
Ẹ má ṣolè bíi ti Gbàdà
Ẹ má kọ̀ṣẹ́kúṣẹ́ lọ́wọ́ Gbàdà
Ohun tí ojú olè ń rí kì í dára
Ojú olè rèé!
Ègbè: Oolè è è
Èlé: Ojú olè rèé!
Ègbè: Oolè è è
Èlé: Ẹ̀yin akẹgbẹ́ mi
Ẹ má ṣolè bíi ti Gbàdà
Ẹ má kọ̀ṣẹ́kíṣẹ́ lọ́wọ́ Gbàdà
Ohun tí ojú olè ń rí kì í dára.

## Àsomọ́ III

### Èka-Èdè Ọ̀gbàgì

Baba kéè súnhun kọ̀nkọ̀n
Pé ìyọn ìyálé un mọ̀ ṣọ̀nìyọ̀n
Mìí fẹ́ Baba tọ́n nùjà bẹ̀rẹ̀
Mìí fẹ́ Baba tọ́n nasọ̀ bẹ́ yọ
Oko kòkó nó fùjà
Ọ̀ ọ́ kúhun kí nálẹ̀ ké tó ó pín
Nì mí yá jòkó tì
Ùjà bẹ̀rẹ̀
Asọ̀ bẹ̀rẹ̀
Kiní mi tutùù
Kiní mi tutu.

### Yorùbá Àjùmọ̀lò

Baba ní kò sí wàhálà
Pé àwọn ìyálé òun ṣènìyàn
Mo fẹ́ Baba tán nìjà bẹ̀rẹ̀
Mo fẹ́ Baba tán lasọ̀ bẹ́ yọ
Oko kòkó ló fàjà
Wọn lóhun tó wà nílẹ̀ kí ó tó ó pín
Ni mo wá jókòó tì
Ìjà bẹ̀rẹ̀
Asọ̀ bẹ̀rẹ̀
Kiní mi tutùù
Kiní mi tutùù.

## Àsomọ́ IV

### Èka-Èdè Ọ̀gbàgì

Èlé: Ọmọ Ajúta a a
Ọmọ Ajúta a a
Ṣé ẹ̀ẹ́ mọhun kó ṣẹlẹ̀
Nípa ọ̀gá rin kọ̀n
Kó jólóyè núlùú?
Ó wùwà ké sunhọ̀n
Ọ̀gá a tíṣà kọ̀n
Ní ṣùkúrù Ajúta
Hàà! Ní ṣùkúrù Ajúta
Nó ti mọ́mọ mábẹ̀ igi ọ̀pẹ̀
Kó ké e yáa gbà nábẹ́
Ó bòbò jẹ ò ó bòbò jẹ
Chief Kórewọ̀lú bòbò jẹ
Ègbè: Ó bòbò jẹ ò ó bòbò jẹ
Chief Kórewọ̀lú bòbò jẹ.

### Yorùbá Àjùmọ̀lò

Èlé: Ọmọ Ajúta a a
Ọmọ Ajúta a a
Ṣé ẹ mohun tó ṣẹlẹ̀
Nípa ọ̀gá yín kan
Tó jólóyè nínú ìlú?
Ó hùwà tí ò dára
Ọ̀gá a tíṣà kan
Ní ṣùkúrù Ajúta
Háà! Ní ṣùkúrù Ajúta
Ló ti mú ọmọ mábẹ̀ igi ọ̀pẹ
Tó ń bá a ní àjọṣepọ̀
Ó bòbò jẹ ò ó bòbò jẹ
Chief Kórewọ̀lú bòbò jẹ
Ègbè: Ó bòbò jẹ ò ó bòbò jẹ
Chief Kórewọ̀lú bòbò jẹ.

## Àsomọ́ V

### Èka-Èdè Ọ̀gbàgì

Èlé: Ìwòí èṣí
NỌba ria sá lọ
Ègbè: Ó sá lọ
Èlé: É dúró bÒgún
Kárùn rá lọ tèfètèfè
Kọ̀lọ̀kadà mọ́ ṣubú nórí títì
Kónímọ́tò mọ́ ṣubú nórí títì
Kí ásídẹ́ntì mọ́ họ̀lú ra
Ọba ra bá họ
Ègbè: Háà, ó sá lọ
Èlé: Ó kọ́mọ Jésù mọ̀ í bỌ̀gún
Ègbè: Mìí dè gbọ́ tuntun
Jésù nOlùgbàlà Ọba ra
Ọ̀rọ̀n mọ̀ nèí irá Ọ̀gbàgì
Kahun ka ná ṣèí sí ò lẹ́gbẹ́mi?

### Yorùbá Àjùmọ̀lò

Èlé: Ìwòyí ọdún tí ó kọjá
Ni Ọba wa sá lọ
Ègbè: Ó sá lọ
Èlé: Kò dúró bọ Ògún
Kárùn rá lọ tèfètèfè
Kọ̀lọ̀kadà má ṣubú lórí títì
Kónímọ́tò má ṣubú lórí títì
Kí ásídẹ́ǹtì má wọ̀lú wa
Ọba wa bá họ
Ègbè: Háà, ó sá lọ
Èlé: Ó lọ́mọ Jésù kì í bỌ̀gún
Ègbè: Mo tún gbọ́ titun
Jésù lOlùgbàlà Ọba wa
Ọ̀ràn mà nìyí ará ìlú Ọ̀gbàgì
Kí la fẹ́ ṣèyí sí o akẹgbẹ́ mi?

## Àsomọ́ VI

### Èka-Èdè Ọ̀gbàgì

Èlé: Oge ọ̀rọ̀n
Oge àbùkù
Ó dúdú nẹ́sẹ̀ ẹ̀

### Yorùbá Àjùmọ̀lò

Èlé: Oge ọ̀ràn
Oge àbùkù
Ó dúdú lẹ́sẹ̀ ẹ̀

Ó pupa nọ́ra a
Ọra dọra fáǹtà à
Ọra dọra kókì ì
Àhọ̀ dà bíi ti kàlákìní ò ò ò
Onúyà ni Bọ́sẹ̀ ẹ̀
Eléṣì ni yèyé Búkì ì
Ó ṣádé orí rẹ̀ nù
Ó kọ̀yìn sọ́là a rẹ̀
Irá ulé mọ̀ tẹ́rìrà
Nójú ìyàó eléṣì

Ó pupa lára a
Ara dara fáǹtà à
Ara dara kóòkì
Àwọ̀ dà bíi ti kàlákìnní ò ò ò
Oníyà ni Bósẹ̀ ẹ̀
Alábùkù ni ìyá Búkì ì
Ó ṣádé orí rẹ̀ dànù
Ó kẹ̀yìn sọ́là a rẹ̀
Ara ilé mà téèrà
Lójú ìyàwó alábùkù

**Àsomọ́ VII**

**Èka-Èdè Ọ̀gbàgì**

Èlé: Nálalẹ́ nọ̀ í wó o
Nágo mẹ́sàn-án nẹ́gbẹ̀ẹ́ ulé iye ọba
Ègbè: Ìrì wọ̀wọ̀ ọ̀
Èlé: Gèlè obùnrin-in
Gèlè obùnrin mọ̀ dàmútẹ́ ò e e
Irá ulé iye ọba kẹ́ẹ̀ í hò?
Ègbè: Uṣẹ́ lílá í nẹ́gbẹ̀ẹ́ ulé rin
Èlé: Ọ̀ ọ́ sẹ̀gbẹ́ ulé iye ọba di hòtẹ́ẹ̀lì
Kọ̀ ọ́ málalẹ́ í nọ́.

**Yorùbá Àjùmọ̀lò**

Èlé: Lálalẹ́ ni wọ́n ń wó o
Láago mẹ́sàn-án lẹ́gbẹ̀ẹ́ ilé ìyá ọba
Ègbè: Ìrì wọ̀wọ̀ ọ̀
Èlé: Gèlè obìnrin-in
Gèlè obìnrin mà dàmútẹ̀ ò e e
Olùgbé ilé ìyá ọba kí lẹ̀ ń wò?
Ègbè: Iṣẹ́ ńlá wà lẹ́gbẹ̀ẹ́ ilé yín
Èlé: Wọ́n sẹ̀gbẹ́ ilé ìyá ọba di hòtẹ́ẹ̀lì
Tí wọ́n ń falaalẹ́ ná.

**Àsomọ́ VIII**

**Èka-Èdè Ọ̀gbàgì**

Èlé: À! Ọ̀mẹ̀nẹ̀kẹ̀n, mí dè ṣe
Gbọkọ ọlọ́kọ rè, Ọ̀mẹ̀nẹ̀kẹ̀n
Ègbè: Ṣé í pani ni kó dè ṣe?
Èlé: Okó jọkó yá bọ́kọ̀ rẹ̀
Ègbè: Ṣé í pani ni kó dè ṣe?
Èlé: Ojú aṣẹ́hó gbébe kọ̀n irá mi kete
Ùka kọ̀n í gbùdí alágbèrè rọn.

**Yorùbá Àjùmọ̀lò**

Èlé: À! Ọ̀mẹ̀nẹ̀kẹ̀n, mi ò ṣe
Fi ọkọ ọlọ́kọ sílẹ̀, Ọ̀mẹ̀nẹ̀kẹ̀n
Ègbè: Ṣé ó ń pani ni tí o ò tún fi ṣe?
Èlé: Ọkọ jọkọ lọ bọ́kọ̀ọ̀ rẹ
Ègbè: Ṣé ó ń pani ni tí o ò fi ṣe mọ́?
Èlé: Ojú aṣẹ́wó ò gbébi kan ènìyàn mi gbogbo
Ìka kan kì í wọ̀dí alágbèrè wọn.

**Àsomọ́ IX**

**Èka-Èdè Ọ̀gbàgì**

Èlé: Ọ̀rọ̀ nì mì í bá í bọ̀ kẹ̀ é kó pé mi
Òkété ṣe press up ó ṣe
Àrà mọ̀ nèí lẹ́gbẹ́ mi
Ègbè: Mọ́ńdè ṣe press up ó ṣe
Èlé: Mì í dákun ṣíọ̀ ariho.

**Yorùbá Àjùmọ̀lò**

Èlé: Ọ̀rọ̀ ni mò ń bá bọ̀ tẹ́ ẹ ló pé mi
Òkété ṣe press up ó ṣe
Àrà mà nìyí akẹgbẹ́ mi
Ègbè: Mọ́ńdè ṣe press up ó ṣe
Èlé: Mo rọra dákẹ́ ariwo.

**Ìwé-Ìtọ́kasí**


Adébọ̀wálé, O. (1999). *Ọgbọ́n òǹkọ̀wé alátinúdá*. Lagos: The Capstone Publications.

Adéyẹmí, L. (2006). *Tíọ́rì lítíréṣọ̀ ní èdè Yorùbá*. Ìjẹ̀bú-Òde: Shebíotimọ Publications.

Adéọ̀ṣun, H. O. (2016). Bátànì àti ìlò-èdè nínú orin ẹgbẹ́ ẹlẹ́mu. *Láàǹgbàsà*, *20*, 70-73.

Ajíbóyè, O. (2003). *Ìmọ̀ ìṣọwọ́-lò-èdè*. Lagos: Tomfetes Publishers.

Awólúsì, Y. (2012). Àgbéyẹ̀wò kókó-ọ̀rọ̀ àti ìṣọ́wọ́lò-èdè inú orin Fẹ́mi Àríyọ̀ àti Oníléọ̀lá Dáhunsí. Ph.D Dessertation. Department of Linguistics and African Languages, O.A.U, Ilé-Ifẹ̀.

Bákàrè, W. T. (2025). Àgbéyẹ̀wò orin Túnlá ní Ìlú Ọ̀gbàgì-Àkókó. *Yorùbá Gbòde*, *8*(2), 223-242.

*Ondo Journal of Arts, Faculty of Arts, Adeyemi Federal University of Education, Ondo. Vol. 2. No. 1&2, 2026* | Àgbéyẹ̀wò Ìṣọwọ́lò-Èdè Inú Orin Àjàgbó ní Ọ̀gbàgì-Àkókó

Dáramọ́lá, O. àti B. Jéjé (1967). *Àṣà àti òrìṣà Yorùbá.* Ìbàdàn: Oníbọnòjé Press Ltd.

Dèlànọ̀, I. O. (1958). *Òwe l'ẹṣin ọ̀rọ̀*. Ìbàdàn: Oxford University Press.

Escarpit, R. (1968). Sociology of literature. *Encyclopedia of Social Science*, *9*, 415-425.

Escarpit, R. (1971). *Sociology of literature*. London: Frank Class and Company Limited.

Ọlátúnjí, O. (1984). *Features of Yorùbá oral poetry*. Ìbàdàn: U.P.L.

Ọláwálé, D. (2015), *Ọ̀nà àbùjá sí àtúpalẹ̀ ewì Yorùbá*. Ìkìrun: Ifẹ̀-Olú Press.

Ọláwálé, H. (2021). Àgbéyẹ̀wò ìlò-èdè nínú orin ìbílẹ̀ Ìlọrin. *Yorùbá Studies Review*, *6*(1), 253-272.

Ọ̀pẹ́fèyítìmí, A. (2014). *Tíórì àti ìmọ̀ ìsọwọ́lò-èdè*. Ilé-Ifẹ̀: Ọbáfémi Awólọ́wọ̀ University Press.

Raji, S. M. (2015). *Ìtúpalẹ̀ èdè, àṣà àti lítíréṣọ̀ Yorùbá.* Ìbàdàn: Oníbọnòjé Press.

Riffaterre, M. (1959). Criteria for style analysis. *WORD: Journal of International Linguistics Assocviation*, *15*(1), 154-174.